ADURA FUN ỌSẸ YI

Edumare Ọba Ogo jẹki ire ile aiye se oju wa kasi je nibẹ pẹlu alafia ati ilera.

# IRANỌ ★ OBOKUN

OWE ỌSẸ YI

Banuso ma ba enia sọ, enia ko si mọ, aiye ti d'eke.

Vol 3 No. 132 ILESHA, MONDAY, APRIL 4 1955. IYE OWO: TỌRỌ


## WON TI SI OMI ERO TI ILESA PELU ASE IJOBA—WO OJU IWE 4



ALHAJI MUSA SARUMI
(Alias Ọlọrun ni basiri)
On je ọkan pataki ninu awọn Ẹgbẹ Nawairu deen ti o wa si ibi oku baba Wahabi Fajinmi.

### ỌRỌ ỌLỌLA FADAHUNSI NIPA AWỌN AJẸLẸ

Lati fesi si ọrọ ti Ọgbẹni Donald Ade Ariyọ kọ sinu iwe irohin kan ni Ibadan laipe yi nipa ọrọ ti Ọlọla J. O. Fadahunsi sọ ni igbimọ isofin nipa awọn osise ijọba ti ki je ise kun oju owo osu wọn, Ọlọla na fi ẹda ọrọ rẹ to sọ ni igbimọ sọwọ lede Gẹsi ati ti Yoruba. Ọrọ na ka wipe:-

Alaga, mo ni ọrọ lati sọ lori isọri 325 ọsẹ kini nibiti wọn ti pese ẹgbẹrun mẹrinla poun ati ọgọjọ poun (£14,160) sinu eto inawo lati fi sanwo osu awọn onisẹ Ijọba mẹjọ.

Mo rope awọn onisẹ Ijọba na je awọn Rẹsidẹnti ati awọn Rẹsidẹnti agba. Ọrọ na nṣe mi ni kayefi pe ipalara ni awọn ọga onisẹ ijọba wọnyi je si eto inawo ti Ẹkun yi papa awọn ti ko nṣisẹ sin orilẹ ede yi ni ọna ti o yẹ.

O dabi ẹnipe isẹ wọn ko wulo mọ. Kini wiwulo ẹniti o nṣisẹ Rẹsidẹnti ni Province ti ipinlẹ rẹ je mẹta to si kọ ọkan ninu awọn ipinlẹ nati patapata ti o si nda idarudapọ ati aifọkanbalẹ silẹ ibomiran ninu Province na.

Larin gbogbo asiko ti o nsisẹ nibẹ, kosi akọsilẹ pe o bẹ igbimọ ijọba tabi igbimọ osisẹ tabi awọn oloye ibẹ wo lati ba wọn forowerọ lori awọn ọrọ ti o kan awọn ipinlẹ na.

Ohun ti o nṣe ni igbafẹfẹ ipari ọsẹ nigbati o ma nlọ si awọn agbegbe lati se faji ti o si npada si ibiti o fi se ibudo laise nkankan fun awọn ipinlẹ na. Bẹni o ni lati gba

Berẹ ni oju iwe 3



STEPHEN AKINBOLAGBE
On je ọkan ninu awọn to wọle laini alatako ni Irẹpọdun Local council. On na wa sibi asẹyẹ sisi omi ẹrọ.

## LOCAL ELECTION RESULTS

| COUNCIL | Chief | NCNC | AG | Ind: | Vacant |
|---|---|---|---|---|---|
| Ilesha Urban District Council | 12 | 36 | 0 | 0 | 0 |
| Ipetu/Ikeji Local Council | 6 | 18 | 0 | 0 | 0 |
| Ibokun Local Council | 6 | 9 | 2 | 7 | 0 |
| Ijebu/Ijesha Local Council | 6 | 14 | 3 | 1 | 0 |
| Kiriji Local Council | 6 | 0 | 11 | 7 | 0 |
| Irẹpọdun Local Council | 6 | 16 | 2 | 0 | 0 |
| Iwara Local Council | 6 | 13 | 3 | 0 | 2 |
| Ifẹwara Local Council | 4 | 2 | 0 | 10 | 0 |
| Erin Local Council | 4 | 9 | 3 | 0 | 0 |
| Oke-Bode Local Council | 6 | 12 | 2 | 1 | 3 |
| Aiyegunlẹ Local Council | 6 | 4 | 10 | 3 | 1 |
| Muroko Local Council | 6 | 18 | 0 | 0 | 0 |
| Ẹsa Oke Local Council | 4 | 2 | 10 | 0 | 0 |
| Oshun Local Council | 6 | 14 | 3 | 1 | 0 |
| Aiyetoro Local Council | 6 | 11 | 0 | 6 | 1 |
| Ifẹlodun Local Council | 6 | 6 | 0 | 0 | 12 |
| Ilupeju Local Council | 6 | 14 | 4 | 0 | 0 |
| Itagunmodi Local Council | 6 | 13 | 2 | 0 | 3 |
| Isaobi Local Council | 4 | 11 | 1 | 0 | 0 |
| Ibodi Local Council | 4 | 12 | 0 | 0 | 0 |
| Aiyepeju Local Council | 6 | 14 | 4 | 0 | 0 |
| Total | 122 | 248 | 60 | 36 | 22 |

Ni igbimọ Oke-Bode, Aiyetoro ati Itagunmodi, awọn Ọyọ to ni ibugbe sibẹ kọ lati yan Kansẹlọ larin ara wọn. Nipa bẹ aye wọn mẹta lo sofo ni igbimọ Oke-Bode, ọkan sofo ni igbimọ Aiyetoro, mẹta sofo ni igbimọ Itagunmodi. Ni igbimọ Ifẹlodun awọn mejila pẹ lati mu oruko wa, nipa bẹ aye wọn sofo.

### ITẸSIWAJU ILẸ IJẸSA ATI AWỌN OSELU WA
[Lati Ọwọ D. A. Ariyọ]

Mo sọ ninu iwe mi ọsẹ ti o koja wipe inu wa yio dun ti awọn Oselu Kansẹlọ ẹgbẹ Alakukọ bale se aleye idi re ti owo ori ilẹ Ijẹsa se ga ju gbogbo ilu miran lọ botilẹ je wipe kosi anfani kan tabi nkan pataki ti Ijọba se fun asanwori. Inu wa yio si dun ti awọn ẹgbẹ yi baler wipe wọn mu ileri wọn sẹ ni ọdun yi nipa lati riwipe owo ori wa dinku, ati wipe wọn se ọna wa, ibusọ ọkọ, ile iyagbẹ ina, omi si gbogbo adugbo tonsan owo omi, ati lati riwi pe ani ọpọlọpọ anfani ti awọn asawowori ilu miran ni Laisi eyi, ko si enia ti yio gba ẹgbẹ yi gbọ ni ọjọ iwaju nitori awibẹ so bẹ ni Ijẹsanwa

Mo si fẹ ki awọn Oselu wa fi ẹmi otọ, ifẹ ilu, ati ibẹru Ọlọrun se isẹ ilu laisi ọta ati ikorira. Ko yẹ kosi tọ ki wọn se ojusaju ni gbogbo ise wọn si awọn onisẹ Ijọba Ibilẹ ati awọn ara ilu.

Ninu osu diẹ si awọn Oselu wa yio ma bẹrẹ si se eto bibu owo ori le asanwori lori, ko yẹ kosi tọ ki wọn se abule giga le awọn ọmọ ẹgbẹ miran lori nitoripe ki se ọmọ ẹgbẹ Akukọ tabi Ọpẹ iru eyi ti sẹlẹ ni ki ibo dadi tode, gbogbo wọn lo mo ile Lori ọmọ adugbo yiya bẹni gbogbo wọn lo mọ ọdọ agba adugbo lati de, wọn si tun gbọdọ ma jabọ fun wọn ninu ohun gbogbo. Emi ni igbagbọ wipe eti ilu ko ni da si ọrọ ilu bi ti ẹhin wa ni-

Bere ni oju iwe 3



D. O. FAMOGBIYELE

On je ọkan pataki ninu awọn Kontirakitọ ni ilẹ Ijẹsa On na wa sibi asẹyẹ sisi omi ẹrọ.

## WAHABI FAJINMI ṢE ỌJỌ MẸJỌ OKU BABA RẸ

Ni ọjọ alamisi ti o kọja ti i ṣe 17/3/55, ni agbọ iku Baba arakunrin Wahabi ni il rẹ ni adugbo Ẹrẹja Ilesa. Lati igbana ni Wahabi ati ẹgbọn rẹ ti nṣe imurasi ẹ fun ati ṣe ọjọ mẹjọ oku na gẹgẹbi aṣa Muslimu.

Ni owurọ ọjọ alamisi na ni awọn enia ti nwọ lọ si ilu Baba Wahibi na eyiti nṣe Ẹdẹ, lati lọ ba wọn ṣe ọjọ mẹjọ na, bẹna tun ni awọn ara ilu ologbe na nwa nki ọmọloku na pẹlu, ile ko gba awọn enia tobẹ ti nwọn tun fi ntọrọ awọn ile ti o sun mọ tosi ile wọn pẹlu.

Orisirisi awọn ẹgbẹ ni o wa si ibi ọjọ mẹjọ baba na nitoripe baba na jẹ ọmu rere enia ati olufọkansin ni igba aiye rẹ. Gbogbo awọn ẹgbẹ Nawa-iru-deen ti Ilesa ni o wa si ibi oku na ati awọn ẹgbẹ Alhaji Ẹdẹ ti ṣe ẹgbẹ ọmọ Baba na, ati awọn ẹgbẹ Muslim Youth Society ti iṣe ẹgbẹ Wahabi ọmọ rẹ.

Ẹniti a si fi ṣe alaga ibi ijoko na ni Alhaji Balogun, ẹniti o ṣe wasu nibẹ ni Alfa Orimogunjẹ, lẹhin iwaṣu na ni Alfa Akodu wa nṣe adura ọpọlọpọ fun oku na lati ọwọ awọn Janma, ọpọlọpọ awọn ti o mu owo wa ko niye tobẹ ti wọn ko le fi darukọ awọn ẹlomiran tan.

Ọkọ ti a nu wa lati Ilesa lọ si Ẹdẹ fun ti oku na jẹ mẹrin ninu awọn ọkọ na ni Bus Ọmọle wa ti osi kun fun ọpọlọpọ ero bẹni awọn ẹgbẹ Muslim Youth Society ṣe bẹbẹ nibi oku Baba ọkan ni nu wọn nitoripe Wahabi na pẹ lu jẹ oloye kan pataki ninu ẹgbẹ na ọpọlọpọ awọn enia ti o wa lati idalẹ ni oti losi Ilu wọn ki oto to agogo mejila.

Diẹ ninu oruko awọn ọmọ ti oku na fi silẹ niwọnyi:- Alhaji S. T. Azeez (alais Alaji Akorede) Wahabi, Fajinmi, Musihatu Fajinmi, Muhamọ Fajinmi, Dauda Fajinmi.

# AKIYESI

## FUN GBOGBO ỌMỌ ẸGBẸ NCNC-ẸGBẸ AKUKỌ

A fẹ ki gbogbo ọmọ ẹgbẹ NCNC mọ pe ipade ọjọ-mẹjọ-mẹjọ ti a nṣe ni Wednesday ko yi pada: nitorina ki gbogbo ọmọ ẹgbẹ fi sọkan lati ma wa si gbogbo ipade dede.



ARABIRIN B. T. OGUNSITEYAN

On jẹ ọkan ninu awọn aṣaju awọn obirin ni Ilẹ Ijẹṣa.



ALHAJI H. R. A. SMITH

On ni alaga ẹgbẹ awọn Musulumi ni gbogbo ayika Ilẹ Naijiria.

## ITAN AWỌN OROGUN MEJI

(Bẹrẹ lati ọsẹ to kọja

Mo ki ẹnyin ọkawe Irawọ Obukun dada. Mo tun ki Olotu Irawọ Obokun pe ọwọ nyin yio ma roke o, amin. ẹjẹki a ma ba itan wa na lọ ni ọsẹ to kọja a ri ka de ibi ti ọmọde na ti nawọ si ọkunrin ologodo gẹgẹbi ọsin ati ohun orisirisi ti o ba fi ta lọrẹ. Bi iyoku itan na ṣe lọ niyi.

Nigbati ọmọ yi de ile inu iya rẹ dun pupọ. Nitorina gbogbo nkan ti o ba fi ta ọmọ na lọrẹ titi de awọn eru, ni iyawo yi da si mejimeji ti o ko fun iyale rẹ yi. Ṣugbọn kaka ti iyale yi, i ba fi gba orẹ yi bibu ni o bẹrẹ si i bu iyawo rẹ yi pẹrẹ-pẹlẹ o, olọmọ diẹ, o ro pe ọmọ mi ko mọ iru rẹ ṣe ni. Sa ko ara rẹ nwaju mi pẹlu ọrẹ iya rẹ, wẹrẹ bayi ni o ke si ọmọ rẹ pe ki o fi ori le afin Ọba ki o lọ ba Ọba ati iyawo rẹ ta yo gẹgẹbi ọmọ iyale on ti ṣe. Bayi ni ọmọ na fori le afin Ọba, ṣugbọn apayira ni ni wọn pa ọmọ na laye, ṣugbọn sibẹsibẹ Ọba sọ fun ọmọde na ki o wa mọ ọn ji ọja to mbọ. Nigbati ọjọ ọna na pe ọmọde na mura lati lọ ri ọba lọja. Ẹiyẹ to wa lati kọrin fun ọmọ iyale yi: Ṣugbọn ọmọde yi ko feti si orin na rara.

Nigbati ọmọ na de ọja o ri enia gbogbo o si nawọ si ẹniti o dade golu pe on ni ọsin (ọba) Inu bi ọba yi gidigidi, o si paṣẹ pe ki a ti oju ọmọ na yọda, wọn si ki ṣẹ ni ẹhin rẹ. Bayi ni ọmọ na pari igbesi aiye tirẹ si nipa ojukokuro lati ọwọ iya rẹ yi wa.

Bayi ni itan na pari, ẹkọ ti o kọ wa nipe ki o mase ma ṣe keta enikeji wa. Ẹda ko ni aropin, abosi onile di oloro lọla. Olorun ọba nikan ni o mọ ẹhin ọla, ẹda kan ko le mọ. Eniti o ba si ẹbẹ ara rẹ ga iresilẹ ni yio ba a o daju. Lẹhhinna asa ikọbirin jọ ko dara. Ikorira, aṣọ, inunibini, edekoyede, ati aibale ọkan ni o ma nmnwa nigbagbogbo, larin awọn obirin papa, ati larin awọn ọmọ wọn jamba orisirisi ni o si ma ngbẹhin rẹ. Eyi ni ipari itan na, ki ẹniti o ba gbọn, ki o tun ri ọgbọn kọ lara itan yi; ẹ o tun ma gburo mi ni ọjọ miran. O di ọba diẹ na o, Ẹ ku iṣẹ o. Olotu wa ọwọ yin yio ma roke o amin.



OMỌ'BA ADEYOKUNNU

On jẹ ọkan ninu awọn Ọmọ'ba ni Ilẹ Ijẹṣa. On si ni Baba ẹgbẹ fun akopọ ẹgbẹ awọn Akẹkọ ọmọ Ijẹṣa ni a yika Na jir a.

## I IẸSIWAJU 'LẸ IJESHA

(Bere lati oju 1)

gbati ko ṣi asoju fun adugbo kọkan.

Asoju ilu lonko ilu sina, bẹni asoju ilu lonfi ọna han ilu. Aini asoju to ni ifẹ i u lọkan ni ko jẹ ki awọn Ijẹṣa ni gbogbo on ti wọn nfẹ, on losi mu ki owo ori wa ga ju ti Ifẹ, Oṣogbo, Ibadan, Eko ati gbogbo ilu miran lọ.

Awa gẹgẹ bi asanwori ko gbọdọ faye gba oselu kan rara, nitori gbogbo wọn longba owo gere gere ninu owo ori wa Fun apẹrẹ Ọlọla J. O Fadahunsi ati Ọlọla S. A. Akinọla mọ iye owo ti wọn ngba ninu owo ori wa gẹgẹ bi asoju Ileṣa ninu Igbimọ Iwọ Orun, wọn si mọ iye ti wọn ngba gẹgẹ bi owo irinsẹ ati owo miran pẹpẹ Ọlọla C. O. Kọmọla ẹ na le jẹ ki gbogbo wa mọ iye ti on gba ninu owo ori wa gẹgẹ bi asoju Ileṣa ninu Igbimọ asofin Eko. Koto kosi sẹ ki enia ki i ma gba le ni Ẹgbẹrun ponn ni ọdun gẹgẹ bi asoju wa, ki o si tun lọ si ipade ati lọ wa ifasẹhin ilu rẹ.

Bakan na si ni, ko yẹ ki wọn ṣe ojusaju nibi Igbimọ igbani sisẹ tabi ki wọn gbe ọrọ gbigbani sisẹ ni abẹ Ijọba, wa le ori owo abẹtẹlẹ tabi ẹgbẹ oselu, bi wọn ti nse lati ẹh n wa eyi ti fi onfa ija ati rogbodiyan larin awọn oselu wa ti wọn fi fẹrẹ ma gba ara wọn lẹsẹ fi ninu ipade.

Awọn Kansẹlọ wa ko gbọdọ gbe ọrọ lere ọrọ ẹgbẹ nikan, sugbọn o yẹ osi to ki wọn tẹriba fun Ijọba Iwọ Orun, ati Ijọba gbogbo ki wọn si sowọpọ pẹlu wọn ki awọn na le ri anfani gba gẹgẹ bi inu Ọlaju, ko yẹ kosi tọ fun awọn Kansẹlọ lati wa isubu Ijọba Iwọ Orun

Akoko yi yatọ si atijọ, olukuluku, adugbo gbọdọ le sokoto bọ lati bojuto Kansẹlọ adugbo rẹ. O yẹ osi tọ, ki awọ Kansẹlọ ma lọ si ipade Ọmọ ilu ati agba ilu ni adugbo wọn fi nigba gbogbo lati ma jabọ fun wọn, ki eti asanwori ma di si ọrọ ilu. Kise ka yan tan ki wọn joko sile wọu, ki wọn di ọga wa ki wọn si ma se opọlọpọ ofin ti kodara laisọ fun wa. O yẹ osi tọ fun lati ma gba imọran lowọ adugbo lori ọrọ pataki ti yio se ilu ni anfani.

(ko i ti pari)

## ỌRỌ ỌLỌLA FADAHUNSI

Bẹrẹ Lati Oju Iwe 1

owo ti o tobi to ẹgbẹwa poun (£2,000) lọdun.

Nigbati mo pin ẹgbẹrun mẹrin a ati ọgọjọ poun si ọna mẹjọ mo ripe o jẹ ẹgbẹrun ati ẹgbẹrindinlọgbọn poun (£1,770) lọdọdun. Kini wiwu ,o awọn osiṣẹ ti ko ni ṣe iṣẹ kankan, ṣugbọn ti yio ma lọ kakiri laiwo awọn ti o ni lati ma bojuto.

Mo gba pe fifun iru awọn osiṣẹ bẹ laye ni ahẹ ijọba jẹ ifowoṣofo. Nitoribẹ, mo ro pe ti o ba ṣe e ṣe ki inawo ti isọri yi maṣe jẹ gbigba.

## HON. FADAHUNSI'S SPEECH IN ENGLISH

Mr. Chairman Sir. I have something to say on Head 325, item (1) £14,160 for eight Administrative Officers. I suppose these officer are Residents and Senior Residents, I am afraid, Sir, most of these high officials are becoming a burden on the revenue of this Region, especially those who are actually not serving the country in the way they should serve.

They are becoming redundant. What is the use of a Resident who holds the post of acting appointment for a period of twelve months in a Province of three Divisons and actually negnected one of the Divisons and caused confusion and unrest in some other places in the Province.

Throughout the tenure of his office there was no record of any visit either to the Divisional Council or the Executive or the natural rulers in those area to exchange views on any matter affecting the Divisons.

What happened were occasional week-ends when he would go to the district to enjoy himself and then come back to his headquaters doing nothing more for the Divisions. Whereas he is supposed to draw about £2000, because when I divide £14 160 by 8, I found the result to be £1,770 per annum.

What is the use neglecting the people he is supposed to look after I regard this as a waste of revenue to retain such officials like this in our civil service Therefore; I feel that this, if possibie should not be approved.

## AKIYESI PATAKI

### IPADE ẸGBẸ ATUNLUṢE

A fẹ ki gbogbo ọmọ Ẹgbẹ Atunluse mo pe ao ṣe ipade Ẹgbẹ na ni ile Alaga Ẹgbẹ Dadi J. F. Longẹ ti Orinkiran, Ilesa ni Mọnde Ajinde (Easter Monday) ni ọjọ kọkanla oṣu April, 1955 (11-4-55) ni agogo mejila ọsan.

A si bẹ gbogbo ọmọ Ẹgbẹ lati wa si ipade pataki na laiku ẹnikan sẹhin. Ẹgbẹ ti ṣe eto alarinrin fun jijẹ ati mimu ni ọjọ na.

Ki Ọlọrun jẹ ki ọjọ na ba gbogbo wa pẹlu alafia ati ara lile.

## AKIYESI

A fi eyi kede fun gbogbo awọn asoju wa ti mba wa ta iwe iroyin yi pe, asojuk'asoju ti ko ba san owo iwe tirẹ ki o to di ipari Ọsẹ kini ti yio tẹle Oṣu, a o da iwe rẹ duro lai si ifiiọ tabi ifisun.

Nipa aṣẹ
Alabojuto

E ma ka Irawo Obokun, ki e si ma p'olowo oja yin sinu re nitoripe tiyin ni.

# IROHIN BI WỌN TI ṢE SI OMI ẸLẸRỌ TI ILẸṢA



ỌGBẸNI E. A. EKUNṢEITAN

On ni Baba Ẹgbẹ NC NC ayika gbogbo ilẹ Ijẹsa

## WỌN ṢI OMI ẸRỌ NI AṢẸ IJỌBA

Lati nkan bi ọsẹ kan sẹhin ni irohin ti tan kalẹ pe Ọlọla E. A Babalọla, ẹniti o jẹ olusẹto fun eto iṣiṣẹ ninu Ijọba ti Ẹkun Iwọ Orun Naijiria yi o wa si Ilẹṣa lati ṣi omi ẹrọ pẹlu aṣẹ Ijọba ni ọgbọnjọ oṣu to kọja

Lati nkan bi agogo mẹwa abọ owurọ ọjọ Wednesday, ọgbọnjọ oṣuto kọja na ni Ọlọla na ti de. O si ba iwaju gbọngan Obokungbusi pẹlu orișirisi ọṣọ.

Lẹhin igbati wọn ka iwe ti wọn fi ki Ọlọla na kabọ tan ni on na ka ọrọ ti o sọ lori eto iṣẹ rẹ, ti o si fesi si iwe ti wọn fi ki kabọ na.



ỌGBẸNI J. O. GIDIGBI

On jẹ ọkan ninu awọn onisowo ọmọ Ijẹsa. On ni olubata fun ẹgbẹ isowo G. B Ollivant ni Ilẹṣa.

Ninu ọrọ rẹ, o sọ pe omi ẹrọ ti Ilẹṣa ni ekeji ninu awọn omi ẹlẹrọ to tobi ju ni Ẹkun Iwọ Orun Naijiria. O ni o tobi lati to lilo fun iwọn ẹgbẹrun lọna adọrin enia. O ni ibiti omi na nṣan si gba iwọn ẹgbẹrun lọna ẹdẹgbẹtalelọgọta galọn

O ṣe alaye wipe lati nkan bi iwọn maili mẹtala abọ ni wọn ti fa omi na wa, wọn si ṣe oju iponmi rẹ pọ si igbore to bẹ ti ẹnikẹni ko fi ri le rin ju iwọn igba yadi (yard) si ile rẹ ki o to ri omi pọn.

Ọlọla na fi yeni pe Ijọba ti akamọ ti Ilẹṣa ni yio ma ṣe itọju omi na. O sọ pe awọn oṣiṣẹ ti o ti mọ nipa itọju omi ti wa ni Ilẹṣa.

Bẹrẹ Loju Iwe 5



OLOYE S. ADEMOKOYA ỌBA ODO

On na pẹlu gbogbo awọn oloye Ilẹ Ijẹsa ni ile ati agbegbe to wa si ibi aṣeyẹ ṣiṣi omi ẹrọ fun Ilẹṣa:



ỌGBẸNI S. O. BEWAJI

On ni akọwe igbimọ ijọba Ibilẹ. On lo tumọ ọrọ ti Ọlọla E A Babalọla na Ijẹsa sọ.



AGUNLEJIKA KEJI LOJA OKEBODE

On pẹlu ọpọlọpọ awọn loja pataki pataki to wa lati agbegbe sibi aseyẹ ṣiṣi omi ẹrọ ni Ilẹsa ni ọgbọnjọ oṣu to kọja

# PELU AṢE IJỌBA NI OGBONJO OSU TO KỌJA

## ṢIṢI OMI ẸRỌ

(Bẹrẹ lati oju iwe 4)

o si yẹ ki Ijọba Ileṣa ra motọ fun wọn ki wọn le ma ri nkan ti yio ma gbe wọn de ibiti wọn ti fẹ ṣe atunṣe omi ti o ba bajẹ kiakia.



J. O LAWANSON

On ni Akọwe Ẹgbẹ Action Group ni ayika gbogbo ilẹ Ijẹṣa

## IDAHUN RẸ

Ninu idahun Ọlọla na si iwe ti wọn fi ki kabọ, o fi yeni pe ki Ijọba Ẹkun Iwọ Orun ma ṣe inawo abojuto omi ẹrọ na jẹ ohun ti ko ṣe e ṣe, O ni inawo omi ẹrọ ti Ileṣa kere, o ni nitorina on rope owo ti wọn yio ma san fun ko ni pọ.



ỌGBẸNI TUNDE THOMPSON

On jẹ ọkan ninu awọn oṣiṣẹ Grammar School Ileṣa. On na wa sibi aṣeyẹ na.



ALAGBA GABRAEL OGUNLẸYẸ

On ni gbogbo Ijẹṣa mọ ni Olọmọyindoyindo nitori itọju ati ifẹ ti o ni si awọn ọmọde.

Lori ẹgbẹgbẹrun ọna ẹgbẹrun mẹrin poun [£4,000,000] owo itọnaṣe, o ni ọna to de Ileṣa ki iṣe ti Ijẹṣa nikan. O ni o dara tabi ko dara gbogbo enia ni Ileṣa tabi ilu okere miran bi Abẹokuta, Ibadan tabi Ijẹbu-Ode ni yio mọ lara O ni nitorina awọn ko le pin ṣugbọn awọn yio ṣe gbogbo ọna.

O ni on ko le sọ ọjọ, ṣugbọn ninu osu April awọn igbimọ to nṣeto atunṣe ọna yio wa si Ileṣa. O ni on ni alaga igbimọ na. O ni igbimọ Ijọba Ilẹ-Ijẹṣa le fi eto inawo ọna ti wọn fẹ tunṣe han igbimọ na nigbana.

Nipa ọja ati ibusọ-motọ ati atunṣe ọna igboro, Ọlọla na sọpe ijọba Ẹkun Iwọ Orun ko le fun ijọba ibilẹ lowo ṣugbọn wọn le ya wọn lowo

lati fi se wọn.

Ni ipari ọrọ rẹ o ki Ọwa ati gbogbo Ijẹṣa ku orire nitori omi ẹlẹrọ ti wọn ni. O ni aidara omi lo nfa orisirisi ailera. O ni nisisiyi ti omi ẹrọ de Ileṣa aisan yio dinku, olukuluku yio si wa ni ilera lati ma ṣe iṣẹ dada.



ỌGBẸNI S. M. OGUNJULUGBE

On ni Alabojuto fun awọn ilewe to jẹ ti Ijọ C.M.S. On na pẹlu awọn Kansẹlọ to wọle laini alatako sinu Ipetu Ijesa/Ikeji Local Cunocil

O ni bi omi ti jẹ ọkan ninu awọn koseimani on rope gbogbo enia yio fi ifẹ sanwo omi na O ni ọpọlọpọ ilu ni ki ifẹ lati sanwo omi ṣugbọn on ma nbẹ wọn.

(Bẹrẹ ni oju iwe 8)



E A ṢAJUYIGBE

O pẹlu awọn to ti nṣe kansẹlọ ni ilẹ Ijẹṣa lati ọjọ pipẹ. On na wa sibe aṣeyẹ ṣiṣi omi ẹlẹrọ titun na.



ỌGBẸNI S. O. MAKINWA

On ni ọga awọn agbowo ori ni Ilẹ Ijẹṣa. On lo si ṣeto aṣẹ ọsọ siwaju Ghangan Obokungousi ati ọgba Kabiyesi fun aṣeyẹ na.

## ODI ỌWỌ ẸYIN AGBA ILU ILAṢẸ

(Lati Ọwọ Isaac Ọla. Ojo Adifa Street Ilọrin)

Mo ki yin pupọ ẹku bẹ. ki Oluwa fi isẹ yin gbogbo wa Amin. Ejọwọ inu mi yio dun bi ẹba le gba mi laye diẹ lati sọ ọrọ mi yi sinu iwe Irohin oloyinmọmọ ọsẹ yi. Ọrọ nipa ilu Ilaṣẹ N-toripe ninu gbogbo ilu ti mo ti nde lati ibẹrẹ ọdun yi, mo ri gẹgẹ bi wọ ti se kọ ile iwe ti wọn sẹsẹ nkọyi bo ti dara to.

O jẹ nkan iyalẹnu lati ri ile iwe ti kontiraktọ kọ si Ajẹda St Ilaṣẹ ti ko ni ilẹkun ti ko si fere afi aganrandi ni wọn se sibẹ agan-randi awa Ijẹṣa npe ni ẹran-ko jẹ Atunṣe rẹ di ọwọ awọn to wa ni idi rẹ o.

### ẸNI TO BA RAN RẸ LỌWỌ NI ORISA OKE NRAN-LỌWỌ

Lọna keji awọn agba ama pa owe kan, pe, ẹnito ba ran ara rẹ lọwọ ni orisa oke nran lọwọ ToTo O se bi owe o Awa ara ilu Ilaṣẹ ni ile ni oko; ẹ jẹ ki a mura ki a fi ọmọ wa sile Ile'we, ẹ masejẹki a fa ara wa sẹhin Ọlọrun ko ni fa wa sẹhin o Nitori agbajọpọ ọwọ ni afi nsọ aya. Ẹyin agba ilu ọrẹ na di ọwọ yin para Ọba wa Lọja Ilaṣẹ, awọn awọn Ijoye, Ẹgbẹ Atunluse ẹ ba wa tun ilu Ilaṣẹ se nitori igba tiyin ni 'yio, agba ki-wọ lọja kori ọmọ titun wọ (toto o se bi owe) Bo ba dara bayi ẹyin ni ao ma fi darukọ bi ko si dara, ẹyin na ni ao ma darukọ. Emi si gbadura si Ọlọrun lati le jẹki o dara nigba tiyin fi Amin.

Ẹsin iwaju on ni ti ẹhin nwo sare, apẹrẹ ti ẹ ba fi lelẹ on ni ao tẹle, nitorina ki a fi apẹrẹ rere lelẹ o. O to asiko lati dide giri, ẹ jẹki awa ire ilu wa. Titi aiye fi nfo fi lọ lori ẹni a ki gbọ bọun rẹ Ọlọrun mase jẹki ire fo wa o Amin

Lẹkan si mo tun bẹ Ọba wa Lọja Ilaṣẹ ati awọn Ijoye rẹ, pẹlu awọn atunse ati awọn Kansẹlọ atunṣe ilu Ilaṣẹ di ọwọ yin o. Ọlọrun yio tun ile ati ọna onikaluku se o Agba Ijẹṣa ẹ bami ṣami aṣẹ di ọwọ yino.

Inu mi yio dun bi ẹ ba le gba mi laye lati fi itan kekere yi siwaju nyin itan na lọ bayi

Kọ'ọkọlọ kan ti o fẹ fi Akọ se ẹlẹya pe si ibi-ase Ọbẹ ni osi pese silẹ fun Akọ o si da si inu awo pẹrẹsẹ Kọlọkọlọ ya tete la ọbẹ na nitori pe akọ ko le jẹhun ni-nu awo p rese. Akọ ko binu o si pada lọ si ile rẹ.

Lẹhin ijọ melo kan, Akọ pe Kọlọkọlọ si ibi ase ni-gbati kọlọkọlọ de ibẹ o ri pe ẹran ni Akọ da si inu ikoko nla kan ti ẹnu rẹ kere kọlọ-kọlọ kọ le jẹ onjẹ na nito-

(Bẹrẹ Loju Iwe 7)

## AWỌN MUSLIM ṢE IPADE NI MỌSALASI ỌJA

(Lati ọwọ Wahabi L Fajumi)

Ni dede'agogo meje owurọ ni awọn Muslim ti nwọ ni ọna ile Ọlọrun wọn ti o wa ni ọja, (Central Mosque) ni ọjọ kẹtadinlogbọn oṣu yi, fun ipade pataki kan ti wọn fẹ ṣe, ipade ti wọn fẹ ṣe na ni a npe ni Muslim Con-gress, of Nigeria. Ṣugbọn wọn yẹ ipade na, nigbati wọn de ile Ọlọrun wọn ba tan, nitoripe nkan kekere kan lodi wọn lọwọ.

Ṣugbọn sibẹsibẹ wọn ṣe ipade kekere kan eyiti o jẹ ti gbogbo Ilesha ati agbe-gbe rẹ patapata, ẹniti o ṣe alaga ipade na ni Alhaji H R A Smith.

Bi ipade na ti bẹrẹ ni Alhaji Smith dide lati sọrọ o ṣe alaye pupọ lori rogbo-diyan ti on damu aiye nisisiyi; o si fi nye wa ninu ọrọ rẹ wipe awọn ara Mi-sira ti le ọba wọn jade ni ilu Misira wọn si tun tita gbogbo nkan ini rẹ pata-pata laiku nkankan.

O tun sọ idi pataki ti ipade ti wọn fẹ ṣe loni yi ko fi bọsi mọ. Lẹhinna ni Ọgbẹni S Ọlatunji ti nṣe akọwe wa sọrọ diẹ lati fi kin Alhaji Smith lẹhin. Shehu Arowo-jọbẹ wa bere ibere kan wi-pe kini o fa ti ipade na ko fi bọsi, ati wipe kini ko jẹki awọn eleto ipade ti fi sita fun gbogbo enia lati le sọ fun wọn pe ipade na ko ni bọ si mọ?

Lẹhinna ni Alhaji Abudu Karimu lati Oshu wa tun fes o dahun wipe n toribẹ ni Alaga ṣe ṣe gbogbo alaye ti o ti nṣe, o si nfi yẹ ni ninu ọrọ rẹ wipe Alhaji Smith sọ fun gbogbo ipade wipe enia ma nro tirẹ, ṣugbọn Ọlọrun yio ma ro tirẹ pẹlu.

O sọrọ siwaju si wipe ni igba diẹ sẹhin on papa wa ni Minusira ki wọn to le Ọba jade wọn bere lọwọ rẹ wipe ewo lo fẹ ninu ki wọn pa tabi ki wọn le jade, Alhaji H R A Smith nfi yẹ gbogbo ipade lati tete lọ yan aṣoju wọn lati ilu ki'lu ti wọn bati wa, nitoripe ipade yio wa ni Ibadan ni ọjọ mejọ oṣu ti on bọ 3/4/55.

Lẹhin igbati wọn pari ipa-de ti gbogbo ilu tan, ni wọn wa bẹrẹ ti Ilesha ati agbegbe rẹ nikan, ninu ipade na ni Ọgbẹni S. Ọlatunji ti bere lọwọ gbogbo ipade na ni orukọ Alaga wi pe njẹ awọn Muslumi Ilesa ati agbegbe rẹ fẹ ki wọn ma ba ipade yi lọ bi?

Nigbati ọrọ na di ariyan-jiyan, enia bi mẹrin mu alaye wa, Ọgbẹni Ọlatunji ba ni ki a fi ọrọ na si Ibo didi, ati wipe ẹlomiran nfẹ ki wọn ma ṣe ipade na lọ ni ọjọ na gan awọn miran ko si fẹ.

A fi'gbati a dibo lati lẹ̀mọ eyiti a ma ṣe ninu gbogbo awọn imọran ti o wa ni

(Bẹrẹ ni oju iwe 7.)



ỌGBẸNI I. O. AJANAKU

On jẹ ọkan pataki ninu awọn ọmọ Ijẹṣa to nṣowo motọ, o si jẹ ogunagbongbo ninu ẹgbẹ Action-Group ni Ilesa.

## ỌGBẸNI ADETURTON LỌ ṢINKU ANA RẸ NI EKO

Ni ọjọ Satide ọjọ kọkandilogun oṣu yi ni Ọgbẹni John Ade Turton tẹ ọkọ leti ni Ileṣa lọ si Eko lati pẹlu awọn Ẹbi Alagba Candido Darocha. Baba Arabinrin Ẹbun Turton fun isinku Iya Fanny Darocha ti agbe sibi isinmi rẹ ni itẹ-oku-Ikoyi ni ọjọ isinmi ogunjọ March, 1955

A gbọ pe Ọgbẹni John Ade Turton ṣe ojuṣe rẹ nibi aseyẹ igbẹhin fun oku na ti wọn gbe lọ fun isin ikẹhin ni ile isin ti Elẹto ni ita Tinubu Leko, lati ibẹ lọ si Ikoyi:-nibiti wọn ti gbẹ ibojioku Iya agba na si. Agbọ wipe ẹni ọgọrun ọdun- di-marun ni iya wa na nṣe.

Lowurọ ọjọ Monde 21-3-55 Ọgbẹni John Turtou mura pẹlu ọgbẹni Ọbara ti n e oni-sowo ni ọja idumagbo ati awọn arakunrin meji miran wọn wọ mọtọ ayọkẹlẹ lọ dupẹ lọwọ Alaiyeluwa Eleko Adele fun iyẹsi gbẹhin ti o fifnu oku iya agba na nipa fifi ọpa oye rẹ ranṣẹ lati ba oku lọ si ile isin Ijọ Elẹto ti ita Tinubu ati lati i ibẹ lọ si itẹ ni Ikoyi, Bakanna ni awọn enia wọnyi ya ki Oloye Ọba onikorodu Oloye Bajulaiye Onikoro ati awọn enia jakanjakan bẹ gbogbo.

## AGBA ILU ILAṢẸ

(Bẹrẹ lati oju iwe 6)

ripe ẹnu rẹ ko le wọ inu ikoko na, afi ki o ma la eti rẹ tabi ki o ma jẹ eyiti o ba bọ lẹnu akọ Inu bi kọlọkọlọ ṣugbon ko le gbẹsan nitori-pe, on na ti ṣe bẹ si akọ ri, ṣe fun mi ki ngo ṣe fun ọ ni ogun ọrẹ.

Itan yi kọwa wipe ki a ma ran ara wa lọwọ nkan ki nkan ti a ba nṣe lọwọ

Olotu Iwe Irawọ Obokun, Ẹ ku iṣẹ o Ọwọ nyin yio ma rọke o. Ọkọ Oba ko ni ṣa nyin lẹsẹ o. Amin

## IPADE MUSULUMI

Bẹrẹ Lati Oju Iwe Kẹfa

ilẹ yi, awọn ẹniti o fẹ ki a ma si lọ jẹ ogun enia (20) awọn ẹniti ko si jẹ mọkanle-lọgbọn (31).

Awọn enia wa fi ipinnu si wipe ipade na yio di ọgbọn-jọ oju ti ombọ yi, Immam Aliu Amokeoja na jẹ ọkan pataki ninu awọn isọgbe alaga ipade ọjọ na.

A si pari ipade na pẹlu adura lati ẹnu Immam Aliu Amokeọja.

MA RA
Irawo Obokun
LỌSỌSẸ



ARABIRIN A. O. FADAHUNSI

On na jẹ ọkan pataki ninu awọn aṣaju obinrin ni Ilẹ Ijẹṣa.



ỌGBẸNI M. M. POPOOLA

On jẹ ọkan ninu awọn aṣaju letter writter ni Ilẹ Ijẹṣa. On na jẹ ọkan ninu awọn Kansẹlọ to wọle si Isaobi Local Council.

## Ikede Ati Ipolowo Oja Ninu "IRAWO OBKUN"

OJU EWE KINI

| | | | |
|---|---|---|---|
| Igba | 1—12 | 8s. | fun inṣi kan. |
| Igba | 13—25 | 7s. 6s. | „ „ „ |
| Igba | 26—52 | 7s. | „ „ „ |

OJU EWE KEJI

| | | | |
|---|---|---|---|
| Igba | 1—12 | 5s | fun inṣi kan |
| Igba | 13—25 | 4s. 6d. | „ „ „ |
| Igba | 26—52 | 4s. | „ „ „ |

OJU EWE KẸTA

| | | | |
|---|---|---|---|
| Igba | 1—12 | 7s. 6d. | fun insi kan] |
| Igba | 13—25 | 7s. „ | „ „ |
| Igba | 26—52 | 6s. 6d. | „ „ „ |

OJU EWE KẸJỌ

| | | | |
|---|---|---|---|
| Igba | 1—12 | 6s. | fun inṣi.kan |
| Igba | 13—25 | 5s. 6d | „ „ „ |
| Igba | 26—52 | 5s. | „ „ „ |

OJU EWE 4, 5, 6, Ti 7 JẸ OWO KANNA PẸLU TI OJU EWE KEJI.

## NWỌN ṢI OMI ẸRỌ NI AṢẸ IJỌBA

(Ilẹre ni-ojo 5)

O ni on ko ropẹ o yẹ ki on ṣẹṣẹ ma bẹ Ijẹṣa nitori pe on mọ pe wọn lowo wọn si mọ ohun to yẹ lati ṣe.

Ọlọla na fi da Ilẹṣa loju pe ọpọlọpọ ohun anfani miran bi ti omi yi lo tun nbọ. O pari ọrọ rẹ pe ki Ijẹṣa ma ṣe gbagbe pẹpẹiyẹ na to nye ẹyin golu.

Bi o ti pari ọrọ rẹ ni gbogbo enia jade sojude ti Ọlọla na ṣi omi ẹrọ na. Bi o ti usitan ni gbogbo awọn ti wọn fiwe pe wọ lọ si ẹgba Kabiyesi lati fi nkan panu.

Diẹ ninu awọn Oloye pataki to wa nibi aseyẹ na ni Ajimọkọ keji, awọn oloye Ọba nla Ọba-odo Ogboni, Risawẹ, Lẹjẹka, Arise, Loja, Okebode Loja Iṣireyno, Arise ati ọpọlọpọ oloye miran.

Diẹ ninu awọn enia pataki to wa nibẹ ni awọn Ọlọla ati Arabirin J. O. Fadahunsi, Awon Kaeselo M. I Ekundare, E. A. Sajosigbe. S. A. Akinbolagbe, R. A. Awobiyi, M. O Owolabi, D. O. Oṣunloye, S. A Famuyide, Shehu Arowojọbẹ, M. M. Popoola, J J Ibironke, J. M Ajayi Ote

Ati awọn Ọgbẹni Gbadebo Ogunleyẹ, enini ẹkọsko Ijẹṣa mọ ni Olomoyinadun de, E A Ekumẹran, H R A Smith, E T. Okeloja, S Akindele Ojo, J O Gidigbi, J. O Lawson, I. O Ajanaku, Tunde Thompson, S B Farodoye, E O Layemi, D O John P. F. C Mosey, S O Maktowa, (Olori Agboto) S O Bewaji, M O Akinwumi, D. A. Ariyọ, E. A Kalejaiye, S M Ogunjulugbe, Ọmọba Adeyokun, I. A Adedeji ati Dr Russel pẹlu ọpọlọpọ Oyinbo.

## ỌGBẸNI D. L. ADEJUYI GBA ISIMI WALE

Laipẹ yi ni Ọgbẹni D L. Adejuyi gba isimi wa si ilu rẹ lati ibiti oti nṣe iṣẹ akọwe agba nibi iṣẹ awọn oyinbo onikusa (Tin miners) ni Oke-Ọya.

Nigbati ode owa bẹ Ile Iṣẹ Iteẹ wo o si fi ajọ ki awọn oniṣẹ ibẹ.

Ọgbẹni si jẹ ọkan ninu awọn lakoso (Directors) ibi iṣẹ yi ti o ti ṣe ọjọ tirẹ on yio si lọ to osu mẹta ki oto pada si ẹnu iṣẹ rẹ.

## IDASILẸ ẸGBẸ AIFẸ IṢIKA SI ẸRANKO

Laipẹ yi ni a da ẹgbẹ Ika si ẹranko ko dara silẹ ni ilu Ileṣa.

Ninu ipade ti ẹgbẹ yi se ni aipẹ yi, ni a ti yan Ọgbẹni Ọladimeji Ọṣungbure alakoso Ẹgbẹ Ọdọmokunrin gẹgẹ bi akọwe ẹgbẹ na.

Akọwe yi si pe gboogbo awọn enia lati fi ọwọ sowọpọ pẹlu ẹgbẹ yi lati ri wipe ọpọlọpọ ika ti enia nṣe si ẹranko ni Ilesha dinku.



ỌGBẸNI DONALD ADE. ARIYỌ

On ni ẹniti o sọrọ nipa itẹsiwaju ile Ijẹṣa ati awọn Oṣelu. Ni dahun si ọrọ rẹ ninu "Tribune" ni Ọlọla Fadahunsi fi gbe ọrọ to wọ ni Igbimọ Iṣofin jade lọsẹ yi.

## E KA NIPA IJOBA YIN

Laipẹ yi, ile Ijẹṣa yio di ọkan ninu awọn ipinlẹ ti o ni ijọba alajumọ-sepọ nipa nini igbimọ iṣejọba mejilelogun.

Wọn ni "bi egungun ẹni ba njo daradara, ori ẹni a ma ya" Irawọ Obokun lero wipe yio jẹ idunnu olukaluku lati ma ri irohin itẹsiwaju ka nipa igbimọ-ijọba akamọ tirẹ; nitoribẹ, a ti nṣe orisirisi atunṣe ni imurasilẹ lati ma ripe irohin njade ni ọsọsẹ nipa gbogbo awọn ijọba na.

Inu wa yio dun bi ẹnyin ọkawe wa ati aṣoju wa ba fọwọsowọpọ pẹlu wa lati ripe iṣẹ na rọrun ni ṣiṣe

Ọna ti ẹ fi le ran wa lọwọ nipe:-

A fẹ Aṣoju (Agent) ni ilu kọkan.
A fẹ aṣoju si ni Ileṣa.
A fẹ awọn ti yio ma fun wa ni irohin pipe.
A fẹ awọn Ọkawe kun awọn Ọkawe wa.
A fẹ ki awọn ti o mura tan lati ma ba wa ṣowo jẹ awọn ti yio ma sanwo lasiko.

Eto bi olukuluku ṣe le ma ra tabi ma ta iwe wa wa ni isalẹ iwe yi.

| | | |
|---|---|---|
| Deposit | 10 to 50 Copies -- | 10/- |
| | 50 to 100 „ -- | 20/- |
| | 100 to 200 „ -- | 4 -/- |
| Commission:- | 10 to 100 copies | 20o/o (4/- in £1) |
| | 100 to 1000 „ | 25o/o (5/- in £1) |
| From 1000 upwards | | Special arrangement. |

All payments should be made during 1st week in the following month, latest 2nd week after which supply would be cut off without notice.

Deposit could be withdrawn after a month's notice should in case the Agent does not owe any arrears if he or she wishes to discontinue the Agency.

## FUN TITA

Motọ Ayọkẹlẹ (Car) kan wa fun tita. Orukọ motọ ayọkẹlẹ Ina ni HUMBER HAWK.

Gbogbo ẹya ara rẹ lo wa dada, a ko lo ni ilokulo, o si wa ni abẹ itọju nigba gbogbo.

Ẹnikẹni ti o ba ni ifẹ lati yẹwo ki o ri Ọgbẹni J.A AKINYẸMI ni ọgba Grammar School Ilesha ni asiko kasiko

### IGBIMỌ IYANILOWO

Eyi ni lati fi ṣe ikede pe a fẹ ki awọn agbẹ to ti kọwe fun ẹrọ ati ogun ti wọn fi npa korikori lara Koko wa sibi iṣẹ ijọba ni ọjọ kẹfa oṣu yi lati agogo mẹwa soke.

A si bẹ olukuluku lati mu oluduro rẹ dani wa

AKỌWE

## AKIYESI

FUN GBOGBO OMỌ ẸGBẸ ACTION GROUP OPẸ

A fẹ ki gbogbo ọmọ ẹgbẹ Action Group mọ pe ipade ọjọ-mẹjọ-mẹjọ ti a nṣe ni Wednesday ko yi pada nitorina ki gbogbo ọmọ ẹgbẹ fi sọkan lati ma wa gbogbo ipade dede.

AKỌWE

## AKIYESI PATAKI

Ki ẹnikẹni ti o ba fẹ kowe sinu iwe Irawọ Obokun ma kọ orukọ ti on papa njẹ pẹlu adugbo rẹ. Toripe ọpọ iwe ni anri gba laisi orukọ. Eyiti ko basi ni orukọ ako ni tẹ jade.

ALABOJUTO

Printed and Published by Ilesha Press Ltd., B110 & B149 Okesha Street, Ilesha 4 - 4 - 55